# IDAJỌ NIPA YÌNYÍN, EṢU ATl OKUNKUN
## Ẹksodu 9:13-35; 10:1-29
## ẸKỌ 55 --- FUN AGBA

**AKỌSORI: "Nitori eyi pãpa li emi ṣe mu ọ duro, lati fi agbara mi hàn lara rẹ, ati ki a le rohin orukọ mi ká gbogbo aiye" (Ẹksodu 9:16).**

**I Idajọ Keje: Àrá, Yìnyín ati Ina**

1 Ọlọrun kilọ fun Farao nipa ajakalẹ-arun miran ti o n bọ wá sori Egipti bi kò ba ni jẹ ki Israẹli lọ, Ẹksodu 9:13-15
2 A ba Farao wi fun igberaga rẹ, Ẹksodu 9:16, 17; Orin Dafidi 10:2; 119:21; Owe 6:16-19; 16:18
3 Ikilọ naa yoo jẹ aabo fun ẹnikẹni ti o ba gbà a, Ẹksodu 9:18-21; Deuteronomi 33:27; Orin Dafidi 27:5; 46:1-3
4 A ran ajakalẹ-arun buburu ti n pa ẹmi run naa jade, Ẹksodu 9:22-25; Ifihan 8:7
5 Israẹli ko ni ipin ninu ajakalẹ-arun naa, Ẹksodu 9:26; 8:22, 23; 9:4
6 Farao ronupiwada, ṣugbọn Mose ṣiyemeji si eyi, Ẹksodu 9:27-30; Orin Dafidi 34:18; Mika 7:18
7 A da ajakalẹ-arun naa duro, ṣugbọn Farao tun dẹṣẹ si Ọlọrun siwaju si i, Ẹksodu 9:31-35; Oniwasu 8:11

**II Idajọ Kẹjọ: Eeṣú lati Ila-Oorun**

1. Nipa titapa si Ọlọrun, Farao mu idajọ nla wa sori Egipti, eyi si gbé Ọlọrun ga loju awọn ara Egipti ati awọn ọmọ Israẹli, Ẹksodu 10:1, 2; Lefitiku 26:23, 24; Owe 1:24-27
2. A fun Farao ni ikilọ miran ki o baa le ni anfaani lati tẹriba fun aṣẹ Ọlọrun, Ẹksodu 10:3-6
3. Awọn iranṣẹ Farao mọ diẹ ninu agbara Ọlọrun ni ipasẹ Mose, wọn bẹru nitori ti ara wọn, wọn si lọ bẹbẹ fun Israẹli, Ẹksodu 10:7; 7:5; 8:19
4. Farao feti si wọn, ṣugbọn o fẹ ki wọn gbọjẹgẹ pẹlu oun, pẹlu igberaga ọkàn, o ni ki Mose ati Aarọni maa lọ, Ẹksodu 10:8-11
5. Awọn eṣú naa wá lati ila-oorun, Ẹksodu 10:12-15; Ifihan 9:1-6
6. Farao tun ronupiwada, ṣugbọn o yi iwa rẹ pada nigba ti a mu ajakalẹ-arun naa duro, Ẹksodu 10:16-20

**III Idajọ Kẹsan: Okunkun ti a le Fọwọ bà**

7. A ran okunkun fun ọjọ mẹta lai si ikilọ pe o n bọ̀, Ẹksodu 10:21-23; Ifihan 6:12; 16:10; Joẹli 2:1, 2, 31; Marku 13:24, 25
8. Farao tun fẹ ṣe ayidayida, ṣugbọn Mose kò gbà fun un, Ẹksodu 10:24-26
9. Farao sé aya rẹ le, o si fi ibinu wi fun Mose pe ki o má tun wa siwaju oun mọ́, Ẹksodu 10:27-29

## ALAYE

### Àrá, Yìnyín ati Ina

Ẹkọ wa kẹta nipa awọn ajakalẹ-arun lori Egipti, eyi ti a rán lati fi ye wọn pe Ọlọrun Israẹli nikan ṣoṣo ni Ọlọrun otitọ, ati pe a ni lati bu ọlá fun Ọrọ Rẹ̀, ki a si gbọran si I, bẹrẹ pẹlu agbara ti o ju ti ẹda lọ lori awọn nkan ti ko ni ẹmi ti Ọlọrun da. A ran ajakalẹ arun yi sori ibọriṣa awọn ara Egipti, ti wọn n bọ iṣẹ ọwọ Ẹlẹda, ati awọn ẹranko pẹlu kòkòrò. Wọn rò pe omiran ninu awọn oriṣa wọn ni aṣẹ lori ẹ̀dá. A ran idajọ keje lati fi han wọn pe awọn oriṣa Egipti kò ni agbara kankan, ati pe Ọlọrun Israẹli ni o n ṣe akoso gbogbo nkan wọnyi, Ẹni ti Farao ati pupọ ninu awọn ara Egipti sẹ́ pe kò si.

A ran ikilọ si wọn nipa arun yi pẹlu akoko ti yoo de. A sọ fun wọn pe awọn ti ajakalẹ-arun yi ba kọlù, yoo kú; nitori bẹẹ a le ri i pe idajọ yi gbona ju ọpọlọpọ miran ti a le pe ni ajakalẹ-arun ti o n yọ ni lẹnu lasan dipo ki o pa ẹmi run. A da Israẹli si gẹgẹ bi ti iṣaaju niori pe wọn bẹru, wọn si bọla fun Ọlọrun.

### Ọlọrun Aanu

Aanu Ọlọrun jẹ ọkan ninu ẹwa iwa mimọ́ Rẹ̀ ti o tobi ju lọ. A ti ri i ni ibẹrẹ ẹkọ wa, bi a ti fi aanu ati awọn ẹwa iwa mimọ́ Ọlọrun miran han aye nipa lilo orukọ Jehofa ninu ifihan ifẹ Ọlọrun. Oluwa n fẹ kọ́ awọn eniyan wọnyi pe Oun wà, ki i ṣe bi Ọlọrun ti o ni agbara ati ipa nikan, ṣugbọn pe Oun ni iwa miran gbogbo ti o wa titi, eyi ti o le fun ẹni ti o gbagbọ́ ni itunu ati idani loju. Ni tootọ ni O n fẹ fi awamaridi agbara ati ọgbọ́n Rẹ̀ hàn wọn nipa awọn iṣẹ-iyanu; ṣugbọn nipa didá awọn ọmọ Israẹli si kuro ninu awọn ajakalẹ-arun wọnyi ati nipa ikilọ ti o ṣiwaju arun yinyin yi, Oun n fi aanu ati ifẹ Rẹ̀ hàn pẹlu.

Ọlọrun iba ti pa gbogbo orilẹ-ede Egipti run kuro lori ilẹ-aye. O le ṣe bakan naa loni si aye isinsinyi ti o kọ Kristi. Ṣugbọn dipo eyi, O yan lati maa rọ wọn, lati fi inu rere bá wọn lo ki O si maa tọ wọn pẹlu suuru ati ifẹ. Lati igba ti aye ti ṣẹ̀, ni O ti n reti lati gbọ́ ohùn ẹ̀bẹ̀ ti o ti ọkan ẹni ti o ronupiwada wá wi pe, "Ọlọrun ṣãnu fun mi otoṣi

ẹlẹṣẹ,” ki O ba a le dahun wi pe, “A dari ẹ̀ṣẹ rẹ ti o pọ ji.” Ohùn Rẹ̀ ko dakẹ titi di oni! O n wa awọn ti o nù sibẹ! O n fi aanu bá awọn ti o wà lẹhin agbo lo sibẹsibẹ.

**Ironupiwada ti kò ti Ọkàn wá**

Ṣugbọn akoko to fun awọn ara Egipti lati pinnu nigba ti a n rán awọn ajakalẹ-arun si wọn. Awọn ti o kọ aanu Ọlọrun ṣegbe. A sẹgun orilẹ-ede naa paapaa nikẹhin. Ọlọrun n ba olukuluku eniyan lò lati mu un de àyè ti yoo fi ronupiwada. Awọn miran yi pada -- awọn miran si kọ̀. Idajọ Ọlọrun lori Egipti jẹ apẹẹrẹ idajọ ikẹhin ti a o tu jade sori aye lakoko Ipọnju Nla. Ni ọjọ naa pẹlu, awọn ti o ti kọ ohun Ọlọrun yoo sọ̀rọ odi si I; wọn yoo fi I ré, wọn yoo si kọ Ọ, wọn yoo si mu iparun ayeraye wá sori ara wọn nipa gbigba àmì Aṣodisi Kristi.

Farao ronupiwada nigba ti ajakalẹ-arun yi de ogogoro, ṣugbọn Mose mọ̀ daju pe ironupiwada naa ko tọkan wá. Ironupiwada tootọ, ki i mu ki a kaanu fun ẹ̀ṣẹ nikan, ṣugbọn yoo mọ ohun ti aanu Ọlọrun jẹ pẹlu. Ironupiwada tootọ yoo korira ẹ̀ṣẹ, ki i ṣe nitori pe o ri iya ti ẹ̀ṣẹ mu wá -- o korira ẹ̀ṣẹ naa nitori pe ẹlẹṣẹ naa ti ri aanu Ọlọrun gbà. Ironupiwada Farao kò ni gbogbo nkan amuyẹ wọnyi ninu. O ronupiwada ki o baa le bọ́ lọwọ ijiya ẹ̀ṣẹ, ki i si ṣe nitori pe o yan lati jẹ adùn ifẹ Ọlọrun ati lati tẹriba fun aṣẹ Rẹ̀. Mose ri abuku yi, o si fi igboya sọ fun ọba agberaga yi nipa ikuna rẹ. Ironupiwada ti o ti inu ibẹ̀ru wá ki i duro pẹ titi.

**Awọn Eṣú lati Ila-Oorun**

Awọn ara Egipti gbagbọ́ pe bi arun kokoro ti o n ba ohun ọgbin jẹ ba de si wọn, eyi fi han pe awọn oriṣa wọn n binu si wọn. Ṣugbọn Ọlọrun rán eṣú ti o pọ gidigidi ju arunkokoro eyi ti wọn ti ri lọ. O de gẹgẹ bi Mose ti sọtẹlẹ, nitori bẹẹ kò si iyemeji pe Ọlọrun Israẹli ni O ran an. Oriṣa wọn ko ni nkankan ṣe pẹlu eyi ráRá. Bi o si ti jẹ pe o buru ji iriri ti wọn ti ri ni tẹlẹ lọ nipa iru arun bayi, wọn ni lati gbà pe Ọlọrun Israẹli ni O tobi ju gbogbo oriṣa Egipti lọ.

Apẹẹrẹ ironupiwada ti ko ti ọkan wa tun fara han lẹẹkan si i. Farao bẹ Mose ati Aarọni lati ba oun bẹ̀bẹ̀, ṣugbọn ironupiwada rẹ ko pẹ lọ titi. Lẹhin ti a mú ajakalẹ arun naa kuro, o tun sé ọkan rẹ le si Ọlọrun – o sé e le ju ti atẹhin wa lọ -- kò si jẹ ki Israẹli ki o lọ. Farao fẹ ki Ọlọrun mu arun naa kuro jù pe ki oun funra rẹ jẹ iranṣẹ tootọ fun Ọlọrun.

**Okunkun ti a le Fọwọ Bà**

Okunkun bù ẹ̀tẹ lu oriṣa oorun Egipti. Eyi jẹ apẹẹrẹ okunkun ti o n bọ wa bo gbogbo awọn ti kò yi pada si Ọlọrun. Ọjọ mẹta ti wọn fi tàràrà ninu okunkun biribiri ti a fẹrẹ le fi ọwọ di mú, ti a kò si ti gburo rẹ ri, yẹ ki o mu wọn lọ sori eekun wọn pẹlu ironupiwada tootọ. A dá Israẹli si, nitori a ka pe “gbogbo awọn ọmọ Israẹli ni o ni imọlẹ ni ibugbe wọn.”

Ṣugbọn Farao sé aya rẹ le sibẹsibẹ si Ọlọrun; ati nitori ki o baa le gba ara rẹ lọwọ okunkun yi, o sọ fun awọn ọmọ Israẹli pe ki wọn lọ si aginju, gẹgẹ bi wọn ti n fẹ, ṣugbọn ki wọn fi agbo-ẹran wọn silẹ. Mose ni iru ẹmi ti olukuluku Onigbagbọ́ tootọ gbọdọ ni -- ẹmi ijolootọ ti kò gbọdọ bù kuro ninu aṣẹ Ọlọrun. Ọlọrun ti wi pe awọn ati agbo-ẹran wọn ni yoo lọ, Mose si duro lori ọrọ yi, o wi pe, “A ki yio fi ibósẹ-ẹran kan silẹ lẹhin.”

Idahun Mose mu ki aya Farao sé le siwaju si i, aṣẹ Farao pe ki wọn ma ṣe tún ri oju oun mọ́ fi ipo ti ọkan rẹ wà gan an hàn, ipo iṣọtẹ si Ọlọrun nigba gbogbo. Ki i ṣe ohun pataki fun wa lati mọ̀ boya Ọlọrun ti sọ gbogbo eto Rẹ̀ fun Mose, tabi boya igboya igbagbọ (Heberu 11:27) ni o fi dahun pe: “Iwọ fọ rere; emi ki yio tun ri oju rẹ mọ́.” Gbogbo ẹbẹ rẹ niwaju Farao fun idasilẹ Israẹli ti dopin nisinsinyi. Ohun ti o ṣẹlẹ lati igba yi lọ jẹ ifi agbara ṣe ki i ṣe ọran ẹbẹ mọ́. Farao ti fi ọjọ oore-ọfẹ rẹ ṣofo, o si wà ni ipo ti ọkan rẹ fi sé le si i. O ti kuna lati lo ọpọlọpọ anfaani ti Ọlọrun ti fi fun un lati ronupiwada, nisinsinyi o ku idajọ ikẹhin nikan ṣoṣo ti a o rán sori rẹ ati orilẹ-ède alaigbagbọ́ yi.

**Alakoso ti O Gba Itọni**

Ninu gbogbo awọn ẹkọ́ wọnyi lori idajọ ti o de bá Egipti, a ti ri awọn otitọ iyebiye. Dajudaju ohun pupọ ni o wà ninu iwe ti a ti kà ti a o fi yé wa bi Ẹmi Mimọ́ ti n tọ́ wa siwaju si i. Ṣugbọn otitọ kan wà ti a kò le kọja lara rẹ lasan bẹẹ.

Mose jẹ alakoso pataki kan, ti o ni ipinnu fun ara rẹ, o jẹ ẹni ti o ja fáfá ti o si muná; bakan naa ni o si jẹ ẹni ti o ni irẹlẹ ju lọ ni gbogbo aye. Ṣugbọn Mose tun ni iwa rere pataki miran ti a kiyesi ninu igbesi aye rẹ. O ṣọra lati tẹle Ọlọrun ninu ohun gbogbo, ayafi igba kan ṣoṣo ti o ṣe ohun ti o ba ni ninu jẹ́, eyi ti o si jiya gidigidi fun.

“Awa kò si mọ ohun naa ti a o fi sin OLUWA, titi awa o fi de ibẹ.” I ba ti rọrun fun Mose, ti aarẹ ti mú nitori ọran ti o ni pẹlu Farao, ọta Ọlọrun, lati gbọ̀jẹgẹ, oun i ba ti rò pe wọn ṣe oriire lati jade kuro ni Egipti bi lilọ wọn yoo tilẹ mu wọn padanu gbogbo agbo ẹran wọn tabi diẹ ninu wọn.

Ṣugbọn Mose n tẹle Ọlọrun, Ọlọrun si ti wi fun un pe Oun yoo gba Israẹli là. Ọlọrun ṣeleri pe ki i ṣe gbogbo ohun ini awọn ọmọ Israẹli nikan ni wọn yoo mu jade lọ, ṣugbọn wọn yoo gba ọrọ̀ Egipti lọwọ awọn ara Egipti pẹlu. Bi Mose ba ti gbọjẹgẹ eyi fi hàn pe o din agbara Ọlọrun kù. Oun kò mọ bi a o ti ṣe gbogbo nkan wọnyi, ṣugbọn o tẹ ẹ lọrun lati maa tẹle Ọlọrun ni ṣisẹ-n-tẹle titi a o fi mú ifẹ Ọlọrun ṣẹ.

Ẹkọ nla ni o wa ninu koko yi fun wa! Nigba pupọ, ninu igbesi aye wa, "awa kò si mọ ohun na ti a o fi sin OLUWA, titi awa o fi de ibẹ," ṣugbọn o ṣe ni laanu pe nigba pupọ ni a maa n ṣiwaju Oluwa, ti a si n gbọjẹgẹ, nigba ti o jẹ pe ifara-balẹ diẹ si i, i ba mu wa lọ sinu ẹkun-rẹ́rẹ́ ibukun ti Ọlọrun ti pese silẹ fun wa. Igbesi aye awọn eniyan Ọlọrun, lọkunrin ati lobinrin ti wọn jẹ akinkanju fi otitọ kan naa hàn. Bi a bá fẹ jẹ ohun elo aayo lọwọ Ọlọrun, a ni lati fẹ tẹ le E – a kò si gbọdọ sare ṣiwaju Balogun Igbala wa. Oun nikan ni O mọ ohun ti o dara ju lọ fun wa! Oun nikan ni O mọ ohun gbogbo nipa wa! O fẹran wa, O si ni inu didun si ọna wa ju eyi ti ẹnikẹni le ni lọ!

**AWỌN IBEERE**

1. Kin ni arun idajọ keje lori Egipti?
2. A ha kilọ fun wọn tẹlẹ nipa ajakalẹ arun ti o n bọ yi ti wọn i ba fi ni anfaani lati sa lọ kuro labẹ gbigbona ibinu Rẹ̀?
3. Kin ni ibawi ti a ran si Farao funra rẹ ni akoko yi?
4. N jẹ ajakalẹ arun yi pa ẹmi run?
5. Kin ni iha ti Farao kọ si i, kin ni esi ti Mose si fun un?
6. Sọ bi arun ẹkẹjọ ti ri.
7. N jẹ a kilọ fun wọn nipa ajakalẹ arun yi, bawo ni o ṣe wá?
8. Kin ni awọn iranṣẹ Farao sọ fun un nigba ti igbona-igbooru ajakalẹ arun naa kọlu wọn?
9. Ṣe apejuwe ajakalẹ arun ti okunkun ati ohun ti o ṣẹlẹ si Israẹli.
10. Kin ni ọ̀rọ ikẹhin ti Farao sọ fun Mose, esi wo ni Mose si fi fun un?